# OLOYE AWOLOWO NDA BIRA NILU OYINBO




AWOGBA Omode fun Girl, Eyl, Hihu-ehin, Orere. Ra Tire Ni Ile Egbogi — ISE — Olodumare Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St., LAGOS

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

TO CLEAR
Gents Suede Court Shoes, Brown, Black & Grey
Before 50/- Now 42/6
Obtainable at :-
A. B. AKINYẸMI
10A Moloney Bridge St.
LAGOS.

VOL. VIII No. 460. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, MARCH 24, 1956. KỌBỌ MEJI (2d.)

## Oloye Awolowo Nda Bira Nilu Oyinbo

Koṣe f'ẹnu rohin ni irin ajo Oloye Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ jẹ nilu Oyinbo, gbogbo ibi ti nwọn nde ni awọn Oyinbo, pataki-pataki nyombo Alakoso Ijọba Iwọ-Orun (The Prime Minister of The Western Region of Nigeria).

Nigbati Alakoso wa kuro nilu Oyinbo lọ si ilu Amẹrika, ko si botiri ni iyẹsi ti awọn Ọlọla, awọn Olowo arakuyamu ilu Amerika, ṣe fun wọn, ti gbogbo gbajare ohun ti Ọlọla Awolọwọ ba lọ si nṣe kongẹ pẹlu ileri wipe awọn ni ifọkanbalẹ lati ṣe iranlọwọ fun ipinlẹ Iwọ-Orun ni Nigeria nitoripe Ọlọla Awolọwọ ti fi alaye tẹ awọn l'ọrun.

### WỌN NI KI A FI ỌMỌ FUN ẸNITI O LẸHIN

Abawun Ajapa fo s'ode, bi ganaku ẹhin Awun ni a nwi? Irin ajo fun gbajare ti awọn Alakoso Ijọba ilẹ wa Nigeria nihin, ti ma nṣe, ọkan nitẹ aromadahun Ọlọla Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ jẹ. Nilu Oyinbo ni ọkunrin na ṣi wa titi okiki eredi ohun ti o ba lọ ti nf'arahan fun wa ri ni ilẹ wa nihin.

Nigbati awọn ẹni-ọla na yio fi Eko silẹ wọkọ Ofurufu ni Ikẹja, Alakoso Ijọba wa sọ gbolohun ọrọ kan ti o ti fi wa lọkan balẹ, wipe awọn ti ṣe eto gbogbo ohun ti awọn mba lọ, o si daju wipe ire ni alọ ati abọ awọn yio jasi.

Ki Edumare Ọba Ọga Ogo ṣọ wọn fun wa lọhun, ki o si pa ọna mọ fun abọ wọn ni alafia. Amin aṣẹ, bẹni ki o ri.



Oloye Obafemi Awolowo

THE NATIONAL BANK

Of Nigeria Limited.

Ile Ifi Owo pamọsi yi
Nfi ọna owo han ẹni
Bi o ba fẹ jẹ oniṣowo pataki ao
ran ọ lọwọ nipa wipe ao tọ ọ
si Ọna ti o dara, ao la oju rẹ
si Ọna owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni a tun nṣe iranlọwọ fun
gbogbo ọja ilẹ wa ti anta si agbaiye.

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—

The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.

No 73/S.2/ Vol. VI/83.

MINISTRY OF EDUCATION WESTERN REGION

## Women's Training College, Ilesha

### Grade II Domestic Science and Women's Subjects Course.

The entrance examination for admission in April 1956 will be held on March 30th. There will be vacancies for sixteen students. The examination will be held at the Women's Training College, Ilesha. Other centres may be arranged if necessary.

2. All candidates must be sponsored as the selected students will sign an agreement to teach for the Sponsor for four years in the Western Region. Sponsors may be only :

(a) Government
(b) Local Authorities
(c) Voluntary Agencies
(d) Proprietors of private schools.

3. Sponsors should apply to the Principal, Women's Training College, Ilesha for application forms for their candidates. The completed application forms signed by candidates and sumbmitted through their sponsors must be returned to the Principal, Women's Training College, Ilesha before March 30th, 1956.

4. The examination will consist of papers in English and Arithmetic.

5. All candidates must have passed at least a Standard VI examination before applying for admission. Girls who hold the Modern II Certificate will be given preference. Candidates now in Secondary Modern Schools must not apply.

6. The fees each year are:-

£6 per annum for tuition fees, payable to the Treasury
£8 " " " uniform, needlework materials and teaching apparatus, payable to the Principal on arrival.

No correspondence can be entered into regarding the rejection of any candidate.

## Lagos Race Club

### Ere Esin L'eko

Awọn enia ti o ni Tikiti (Tickets) ti a to nomba rẹ si isalẹ yi ni wọn ṣ'oriri jẹ ninu ere ẹṣin ti ao ṣe ni aṣalẹ oni, ni gbangba tẹju, ọdan nilu Eko.

Ẹniti ẹṣin tirẹ ba ṣiwaju yio gba £628, eyiti o ba tẹle yio gba £275, eyiti o ba gba ipo keta yio gba £137. 10s.

Gbogbo awọn ti ẹṣin tiwọn ko ba ya ṣugbọn ti Nọmba wọn yọ, yio gba £3. 3s.

| | | |
|---|---|---|
| Tickets | No | 09350 |
| " | " | 018146 |
| " | " | 06393 |
| " | " | 010126 |
| " | " | 011728 |
| " | " | 016518 |
| " | " | 015801 |
| " | " | 017181 |
| " | " | 08542 |
| " | " | 013020 |
| " | " | 010858 |
| " | " | 04153 |
| " | " | 0597 |
| " | " | 01038 |
| " | " | 02822 |
| " | " | 0196 |
| " | " | 017207 |
| " | " | 0620 |
| " | " | 05738 |

(wo yoku loju ewe kejo)

VOMICURE




A Very Reliable Remedy for Vomiting During Pregnancy. Loss Of Apetite, Pains Below the Abdomen And All Other Ailments That Make Pregnancy Uncomfortable. No Prescription Needed. Just Buy A Bottle And Enjoy Good Health.
Obtainable from:-
EJIWUNMI MED. STORE
LAGOS.
and many other Medicine Stores

## Owo Ori D'oro, O Gbode Nile Ibo

Irohin kah wa wipe ofin owo ori ati owo ori sisan ti'un fun awọn obinrin ti Ijọba Ila-Orun (Eastern Government) gbe jade ninu ipade igbimọ ti nwọn nṣe lọwọlọwọ yi ti da ariwo silẹ, depo ti awọn pataki pataki ninu ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C) ko f'aramọ



NNAMDI AZIKIWE

Ofin titun na bu le owo ori girimọyan o si tun bu le owo ọja rira lẹhin ti Ijọba apapọ (Federal Govt) ti fi kun owo ibode lori awọn ọja to nti ekeji wa eyi mu ki ariwo pọ lori ẹgbẹ Alakukọ (N. C. N. C) wipe wọn ko duro ti adehun ti nwọn ṣe wipe Ijọba ti awọn ko ni fi kun owo ode nisisan laiko fi ba ara ilu jiroro rẹ tẹlẹ.

Iyanu nla ni eyi jẹ fun ẹnikẹni wipe ẹgbẹ Alakukọ ti o ma nṣe atako owo-ode sisan ni o tun wa da ofin owo girimọyan silẹ ni sisan, ti nwọn tun fi ti awọn obinrin kun. Ẹnyin enia wa ṣe ẹ nri oju aiye lode bayi? ko ha yẹ ki ẹ ronu yin wo lori ẹgbẹ Alakukọ yi

## Ija Nla Sele Labu Adegbite

IBADAN. A gbọ wipe Ija kan ṣẹlẹ larin awọn enia abule Adegbitẹ ati awọn Ẹgba nIwọn ibusọ mẹtadinlogun silu Ibadan, lori ẹnu ala ilẹ, ati pe ọrọ akitiyan yi lori ala ilẹ na ti wa laiti wọn ti pẹ.

A gbọ wipe enia kan ku patapata, enia meji ni nwọn fi ṣe awati, ti nwọn ko ri, lẹhinna ni nwọn tun gbe awọn meji wa sile Iwosan ni Adeọyọ fun ọgbẹ ti nwọn f'aragba, a si gbọ wipe ori ewu ni awọn mejeji wa.

Gẹgẹbi a ti gbọ ọrọ na, nwọn ni awọn ara abule ji loru ba ina ti nwọn ti tẹ bọ ile wọn, nibiti nwọn ti nsa asala fun ẹmi wọn ni awọn kan ti tọwọ bọ wọn lara lairotẹlẹ, o wa di b'ọlọ ki o ya fun mi. Enia marun ni ọlọpa mu, nwọn si ti ko awọn ọlọpa lọ si abule na.

Ọrọ ija bi iru eyi ti ṣẹlẹ larin awọn enia na ti adajọ fi so agbejẹ mọ wọn nidi wipe ki wọn ṣe mẹlọ-mẹlọ fun oṣu mẹfa ti wọn ko gbọdọ ṣe ijọngbọn.

Bi a ba ti tun gbọ ọrọ yi si ao ma j'omitoro rẹ si yin leti o.

No. 57.

## Army Entrance Examination for Potential Officers

**The Army Entrance Examination for potential Officers, details of which were published in the press recently, will be held on 17 and 18 May 1956. The examination centres will be at LAGOS, KADUNA, and ENUGU.**

**More detailed information may be had on application to Headquarters Nigeria District, Lagos.**



**Aworan inu iwe wa yi niti Ọgbẹni Ahmadu Sardauna ti Ilu Sokoto on l'ombẹ lọwọ osi yẹn, o wa si Eko ninu ọsẹ tokọja yi, o si ti pada si Ilu rẹ ni Oke - Ọya.**

## Western Region Production Development Board

The Board invites applications for a few Vacancies in the following grades :-

(a) AGRICULTURAL UNIT MANAGERS.
£660 x 42 - £1,070; £1,100 x 55 - £1,320.
(plus expatriation pay, where applicable, as follows) :-
£660 - £868 (basic) - £180
£902 - £1070 " - £240
£1100 - £1320 " - £270.

(b) AGRICULTURAL ASSISTANT UNIT MANAGERS.
£600 x 30 - £750.

(c) AGRICULTURAL SENIOR FIELD ASSISTANTS.
£468 x 24 - £564.

(d) (i) FIELD ASSISTANTS GRADE I.
£231 x 15 - £336; £354 x 18 - £426.
(ii) FIELD ASSISTANTS GRADE II.
£153; £159 x 12 - £201.

In every case point of entry into scales will depend on qualification an experience.

QUALIFICATIONS FOR (A)

A degree or diploma in agriculture plus several years field experience including labour control. Specialised knowledge of cocoa and oil palm would be an advantange. Successful app icants will be required to take charge of large plantations and must be competent in all aspects of plantation management.

QULIFICATIONS FOR (B)

A diploma in agriculture from any recognised local or overseas institutions, familiarity with all aspects of plantation management or sound technical training in agriculture backed by several years of wide experience, in all aspects of plantation management.

QUALIFICATIONS FOR (C)

Senior Cambridge School Leaving Certificate or its equivalent and in addition a diploma from the local Schools of Agriculture and several years of field exprience, including control of labour keeping of farm records and writing reports

QUALIFICATIONS FOR (D)

Senior Cambridge School Leaving Certificate or its equivalent plus technical training in a recognised local Agricultural School. In the case of (d) (i) some years of field exprience is essential.

Applications in applicant's own handwriting should be fowarded to

The Personnel Secretary,
W. R. P. D. Board,
Secretariat,
Ibadan,

to reach him not later than 5th April, 1956.

Only applications of those selected for interview will be acknowledged.

# ELETI OFE
A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS
28, Kosoko Street, Lagos
P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAMS
"ELETI – OFE LAGOS"
Phone 23370

VOL. VIII. NO. 460, LAGOS, SATURDAY MAR. 24, 1956.


## Ode D'ode Wa Oran Ni Won Fi Nda

Gbogbo wa, t'ọmọde ati agba, l'ọkunrin l'obinrin ni a mọ igbadun alafia to mbẹ nilu Eko wa yi pẹlu gbogbo ile ekute, ile ayan an, ati awọn kokoro miran ti awọn alaṣe ilu wa fiṣe okun'fa ile wiwo larin ilu wa yi, ti o jẹ wipe t'awa ti gbogbo kokoro wọnyi ni a ti ngbe pọ ti alafia si to wa lati ẹhin wa.

Ṣugbọn nisisiyi ti o fẹrẹ dabi ẹnipe awọn Oyinbo Gẹsi nfi aye silẹ fun wa lati maa ṣe eto ilu wa yi ni awọn ogunna gbomgbo ti a yan sinu aye igbimọ alaṣẹ Ijọba wa, fi ake k'ọri wipe pẹpẹsẹ nitori ti ilu Eko jẹ olu fun gbogbo Nigeria, awọn nilati sọ ilu na di ilu Komadan; ṣeni ilu Komadan ti a gbọ itan rẹ ki iṣe ọjọ kan ṣoṣo ni awọn enia ibẹ fi sọ di ilu Komadan eyi ti awọn Oyinbo fi p'owe bayi:–

"Rome was not built in a day"

Awa ni ero wipe bi ode ba tilẹ di ode wa, irọrun ati alafia ni awọn enia wa ti wọn ba jẹ alaṣẹ eto ilu wa yio maa wa fun wa, ṣugbọn loni nkọ? a fẹrẹ le sọ wipe ọmọde kọbẹ ra, o ra joni-joni. Eyi maṣe kelebọ o.

Ni ọjọ Tuesday ọsẹ yi ni ogunlọgọ awọn Obinrin pẹlu awọn Ọkunrin to o lọ ba awọn ọlọla Olugbimọ wa ninu ile igbimọ nla (House of Representative) lati fiban gedegbe wipe gbogbo ara ilu Eko ni ko fẹ ti ile wiwo ti wọn da'wọ le yi, yio si jẹ didun inu gbogbo ilu Eko bi awọn alaṣẹ wa ba le da'wọ ile wiwo na duro.

Ako sọ wipe ilu wa ko fẹ atunṣe, ṣugbọn ki a jẹ ki a maṣe atunṣe rẹ diẹ-diẹ ti ko fi ni si ti a nko en a lọ gbe ilu titun, ti wọn ko ni ifẹ lati gbe.

Lẹkansi a tun bẹ awọn alaṣe Ijọba wa, ki nwọn fiye-denu ba wa da ọrọ ile wiwo na ro o.

## AKIYESI PATAKI

Bi o ba fe ra Eleti-Ofe tabi o fe polowo oja sinu re,
LỌ SI:-

**18, Race Course Road,**
OKE–PADI, IBADAN.

E mu irohin wa tabi ohun to ba je edun okan yin, ki e si ma ka Iwe ELETI–OFE nigba gbogbo.

## Enikan ji omo Meta Gbe

IBADAN Ni ọjọ Monday ọsẹ yi ni awọn ọlọpa mu ọmọkunrin kan ti orukọ rẹ nje George Olu, wa siwaju adajọ agba Ọgbẹni Adetokunbọ Ademọla fun ẹsun wipe o ji ọmọ mẹta gbe nilu Ibadan o si ko wọn lọ si Abeokuta lati ọdun kẹta s'ẹhin (1953).

Ọdaran yi bẹ Kotu fun iranlọwọ lati pe ẹlẹri meje ati pe on yio san owo awọn ẹlẹri na. Agb'ẹjọro Ijọba sọ wipe on yio pe ẹlẹri mẹsan nigbati ẹjọ ba bẹrẹ.

Awọn ọmọ ti ọdaran yi ji gbe ni Jimọ Ajani, Lalere Iṣhọla, ati Emmanuel Afọlabi. Adajọ fi riro ẹjọ na si Monday to mbọ.

## Hogan Bassy Nlo Si Amerika

A gbọ wipe Ọgbẹni Hogan (Kid) Bassey abẹ'ṣẹ kun bi ojo yio lọ silu Amẹrika ni ipari oṣu to mbọ lati lọ wa aye ati gba ipo nla eyiti Ọgbẹni Sandy Saddler gba, Olori ẹlẹṣẹ agbaiye.

A ni ireti wipe awọn ogbogi ninu ẹṣẹ jija mẹta ni yio ba f'egun-ko-egun bi o ba besi fun u yio ni aye fun oye nla na, Adura tiwa ni ki o bọsi o'

Ẹnyin ọkawe wa yio ranti wipe Ọgbẹni Hogan (Kid) Bassey yi ni o ba Spider Kelly ja ti o si bori rẹ nilu Oyinbo Gẹsi, ti okiki ija na kan de ọdọ wa nihin.


NO. 55

## Ministry Of Transport.

**It is notified for general information that the Sapele car ferry will be closed down on 24th March 1956 for 4 days for repairs to the ramps. Normal service should be resumed on 28th March, 1956.**

M. H. VARVILL
Permanent Secretary
Ministry of Transport.

Lagos 16th March, 1956.



## Western Region Production Development Board.

# Vacancy For Senior Stores Assistant.

Applications are invited from suitably qualified candidates for a vacant post of Senior Stores Assistant in the Stores Section of the Board. Salary will be in the scale £354 x 18 - £426 per annum, entry point depending on qualifications and experience.

QUALIFICATIONS

Applicants must be fully conversant with Store Rules and procedure. Preference will be given to candidates who possess a thorough knowledge of vehicle-spare parts in respect of at least one of the following; Bedford, Land Rovers, Ferguson Tractors and Trailers.

DUTIES

The selected candidate will be required to undertake, in addition to general store keeping, duties connected with the safe custody of all Board's vehicle spare parts. He will be responsible for the selection of vehicle spare parts and engineering equipment and will be required to enter into a Bond with the Board.

Applications accompanied by copies of certificates and two recent testimonials together with names of Bondsmen should be addressed to :-

The Personnel Secretary,
Western Region Production
Development Board,
Secretariat, Ibadan.

to reach him not later than 15th April, 1956.

Only applications of those selected for interview will be acknowledged.

## Awon Faranse Fe Gba Ina Je

Irohin kan wa wipe, ni ilu Algeria to mbẹ labẹ aṣẹ ijọba Faranse, ni nwọn ti nṣe gbọnmisi omi-ko-to lati ọdun eṣi wa Ede ko yede na bẹrẹ nigbati awọn kan ditẹ mọ ọba ilu Moroko wipe awọn ko fẹ ni Ọba mọ. Ti awọn Faranse gẹgẹbi iṣẹ wọn ko wadi wo, nitoripe ẹniti o ba kọkọ ro jọ ni nwọn ngbe ni ija, nwọn ṣe atilẹhin, wọn le ọba ti nwọn sọ pe awọn ko fẹ lọ silu Madagaska.

Latigba yi wa ni edeko-yede ti bẹrẹ si gbilẹ ni Moroko, titi ija na de ilu Fasi, on na lo tan titi de Tunis, on kanna lo ja ranyin de Algeria.

Ti ilu Algeria yi lo wa peleke, ti o si dabi eyiti apa awọn Faranse ko fẹ ka mọ Nisisiyi ija igboro ilu Moroko fẹ di Ogun ojij nisisiyi nilu Aligeria, Bi o ti le jẹ wipe Ọba ti nwọn wa lọ na, nwọn ti dapada, sibẹ ibinu Ọlọrun koiti dawọ duro.

Gbogbo ọkọ ofurufu ati ọkọ oju omi ni awọn Faranse fi nko awọn ọmọ Ogun wọn wa si Algeria nitoripe bi nwọn ko ba tete ṣe eyi, ija na ylo buru ju ogun Idahọmi lọ. Awọn Faranse ti o fi igbakan jẹ alagbara aiye, dabi eyiti o nfẹ di obinrin, Nitorina Baba ẹgbẹ ilu Faranse sọ pe bi o ti lẹ jẹ wipe akoko yi le fun wọn, sibẹ awọn yio fi han wipe ọkunrin ni Faranse

Ninu ipade kan ti awọn igbimọ ilu Faranse ṣe, nwọn pinu wipe, gbogbo awọn ohun ija ogun bi Agba nla, Ibọn Poo-poo, Bren Gun, Machine Gun, Flame Thrower, Granade, Trench Bomb, Aircraft Gun, Artilery, Bombs ni ki a kolọ si Algeria nitori aibamọ, o le ṣe bẹ di ogun nla ki o ma ba bawọn labo gẹgẹbi ogun Jamani.

A tun gbọ wipe nṣe ni Railway nko ọmọ ogun Faranse lati ilu Paris wa gunlẹ si ebute Mercelles, nwọn o si fi ọkọ oju omi gbe wọn gunlẹ si ebute Algeria. Ẹo ma gbọ bi ọrọ yi ba ti nlọ si.


WESTERN REGION PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD

## Press Notice

**Rubber Processing Factory,**

IKPOBA, BENIN CITY.

**It is notified for general imformation that a large number of applications for employment have already been received by the manager of the above factory and that further applications wil not be required. In the future, such letters will not be acknowledged.**

**M. D. T. FARR**
**Factory Manager.**


## Eniti O Ba Gbo Ede Yoruba Ko Jade

Ọrẹ ti o nkawe yi, njẹ iwọ ba gbọ ede yoruba ndan?. Bi o ba jẹ wipe, bẹni wa danrawo, ki o si tu ede yoruba yi si wẹwẹ.

1. Baba Alabamẹta ba Baba Talabi pe Baba lati wa ṣe gbajamọ fun, baba na si yọ abẹ onibaba nidi, o fi ṣe gbajamọ na, ṣugbọn oruka baba idi ọbẹ na bọ si abẹ ẹwu baba kan ti o joko lẹhin baba alabamẹta.

2. Gbagba ni enia bi Igba gbaruku ti Oloye Igbaruku lẹhin, ti awọn ti igba ademu lọwọ wọn, ọpọ awọn gbajumọ ti o fẹ fi oju jẹ dodo iran na, mu Igba, awọn gun ori ọpẹ lọ, nigba na ni nwọn ri i wipe igba lo mbẹ ninu igba elomiran ni ṣoki, igba Oloye Igbaruku tu wọn lara ju igba ti Oloye gbagba-kunugba lọ.

Lemọmu Ajakuta


Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS



*Read this list of popular titles*

**Read this list of popular titles**

JZ 5873 –Aliburada/Waka Ruwa— Alfa Yinusa Mujiawa (Hausa)
,, 5918 –Governor's Cup/Modesty Mambo)
,, 5919—Alafin/Ejire Modesty Mambo Orchestra
5921 —Oruko Oluwa/Bisi Durosinmi— Yesufu Olatunji & His (Sakara) Band
,, 5922—Orimolusi/Sanusi )
,, 5923 —School Disaster/Mogaji) Ayinde Bakare & His (Juju) Band

,, 5924—Agbehin Tehinse Awon Oba Ilorin)

,, 5924— Gbajumo Ilu/Alaropin S.O.A. Ladipo & His (Korande Group

,, 5927— Olugbenghe/Gbomogbomo — Sule Aregbe & His (Perente) Band.

,, 5929 - Eko Ofe/Rere – Ijesa Mambo Orchestra
JUP 105 – Baba Prado/Ama Kane

,, 106—Wey Ting Na Me I Do/Kron Kron)

,, 107—Ewuraba Betty/Comfort Samba)

,, 108 Hwin Me Ahemamu/Sanbra) King Bruce & His Black Beats

*Sold by all the best stores*

"HIS MASTER'S VOICE" *Yellow label* RECORDS

HIS MASTER'S VOICE

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

## Enia KO Se Finu Han

Lati Ọwọ Ẹsọ Ikoyi

Iji-tagiri tarigi, A w o Ijitarigi Ijitarigi tarigi,
Awo Ijitarigi awọn lo difa fun agbe Ẹlẹmu
Ogogo ti araiye ni awọn yio ba tirẹ jẹ, a ni ki
o rubọ, o gbọ o ru o tubọ, o ṣetutu
Ọwọnrin meji

Ogogo agbe Ẹlẹmu jẹ ọkan ninu awọn ọmọ awo Oriṣa Ogun iṣẹ ẹmu dida lo ma nṣe, bi o ba da ẹmu tan, ki o to gbe lọ si ọja, yio kọkọ dari rẹ fun Oriṣa Ogun. Bayi li o nṣe lojojumọ.

Bi tẹni yio ba sunwọn araiye ko ni le ba jẹ,
Ewe ọmọ ni nlurawọn pẹlẹmbẹ, pẹlẹmbẹ Ewe
agba ni nlurawọn gbankọ, gbankọ a difa fun
Ogogo Ẹlẹmu a bu fun Ọya A ni ki nwọn o
ṣe tutu ki nwọn le la nidi Ọpẹ nwọn gbọ, nwọn
ru. Ọwọnrin meji

Lọjọ kan ti agbe Ogogo gbe ẹmu lọ si ọja ọkunrin ajeji wa tọ ẹmu na wo, nigbati o ri wipe o dun, o ni k i o gbe kalọ. Tẹlẹtẹlẹ Ogogo Ẹlẹmu jẹ Ọdẹ, ko si si ohun kan ti o mba a lẹru. O tẹle ajeji enia yi titi nwọn fi wọ igbo Irunmọlẹ. Nigbati nwọn de ẹnu ala Ile aiye ati Ọrun, Ẹlẹmu duro, ọkunrin na sọ fun wipe, ki o duro de o n titi on yio fi pada de, O lọ ko si pẹ lẹhin n a awọn enia meji pada de, nwọn ba Ogogo Ẹlẹmu ṣe adehun w ipe, lojojumọ ni ki o ma gbe ẹmu wa fun wọn. Bi o ba ti de ihin yi ki o gbe ẹmu na kalẹ ki o si wipe "Ara Ọrun, ara Ọrun mo de o, emi agbe Ẹlẹmu Ogogo" awọn yio si da lohun, Dipo okowo lerugba ti nwọn nta keregbe ẹmu lọja, awọn yio ma san irinwo fun. Bayi ni Agbe Ogogo nṣe lojojumọ.

O wa di ohun iyalẹnu fun awọn Ẹlẹmu ẹgbẹ rẹ wipe, Ogogo ko tun ngbe Ẹmu wa si ọja fun tita mọ, ko si tun si iṣẹ miran ti o tun nṣe ju iṣẹ Agbẹroko lọ, e ha tiri ti o fi nṣe ọmọ enia ju ti nwọn lọ, nwọn bẹrẹ si fi imu finlẹ titi, nwọn ridi rẹ wipe, awọn ara ọrun lo mba ra ẹmu, ko si oriṣi ọna ti nwọn ko gba lati fi ba tirẹ jẹ, nwọn lọ gbẹ Ṣigidi soju ọna, nwọn gbe ẹbọ soju ọna Ko si iru ọna ti nwọn ko gba tan, gbogbo rẹ ni Ogogo nti sọnu.

(Wo yoku loju ewe keje)


## IMORAN FUN EYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ e w a ra ỌMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko chin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

ỌMỌRELA BABY MIXTURE
(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)
O wa Lọdọ :—
COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS



## WESTERN REGION PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD.

## Clerk Of Works.

The Board invites applications for the post of Clerk of Works who will be responsible for the inspection, maintenance and repair of buildings.

Candidates should have served a full apprenticeship in one of the Building trade and served as General Foreman or Contractor's Agent on large contracts, or have had previous experience as a Clerk of Works.

Salary to be paid will depend upon qualifications and experience of the successful candidate and will be in the range of £660; £700 x 42 - £868; £902 x 42 - £1, 070 (plus expatriation allowance where applicable). Point of entry will depend on the candidate's qualification and experience.

Applications, in the applicant's own handwriting, giving full details of qualifications and experience, should be fowarded to :-

The Personnel Secretary,
Western Region Production Development Board, Ibadan,
to reach him not later than the 26th of March, 1956.

Only applications of those selected for interview will be acknowledged.



## Now Available

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS, DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just Write, Call Or
Phone 21372

IKORODU
TRADING
COMPANY

20/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 395) LAGOS.
AND
NEW COURT ROAD,
IBADAN


Polowo Oja
Re Sinu Iwe
Irohin Eleti-Ofe


## MECCA PILGRIMAGE 1956

KANO to JEDDAH

FARE £125.0.0 RETURN

PILGRIM DUES & TAXES £6.6.0

Comfortable four engined D.C. 4. Skymaster Aircraft

Make your booking early at any office of WAAC or appointed agents

WEST AFRICAN AIRWAYS CORPORATION

## Irora Ni Orikerike Iiti Isan Ara
BOYA ARUN IGBAROKO LOFA



Işe ti IDINRIN tabi olo-inu ose ni lati ko bogbo idoti ti o mbe ni ara danu, Bi awọn Kidinrin nwonyi ko ba sise daradara awọn idoti ara na yio ma po si, yio si wa di irora fun enia ni orikerike ninu ara.

Qna ti a le gba fi ba gbogbo arun yi ja ni wipe ki a se iranlowo fun Kidinrin lati sise re egbogi ti a npe ni DE WITT'S yi lo le sise na.

Nitori iru arun bayi ni a sese egbogi na o si jẹ atura o si nfo inu enia mo nipa jije ki Kidinrin bere ise.

A ti dan egbogi DE WITT'S yi wo a si ri wipe o dara, Kakiri gbogbo agbaiye ni a nta Qpolopo iwe ni a ti ri gba nlti odo awon ti arun yi mba ja, ti awon si ti ri iwosan kiakia.

Kini nda o duro ti iwo ko danwo fun irora tire lo si sobu egbogi lo ra okan wo.

Egbogi DE WITT'S dara fun Ehin didun, Irora Orike Laku regbe Igbaroko ati arun Isan ara.

Ohun ti o dawa loju nipe egbogi DE WITT'S yi je cyiti a se toniton! gbogbo egbogi re l'o si dara.




**DE WITT'S PILLS**
**for Kidney and Bladder Troubles**


## Enia Ko Se Finu Han
( O Bẹrẹ l'oju ewe Kẹfa )

Ogogo ni Ọmọkunrin kan ti a npe ni Ọya, ti o ma nroko fun nigbati Ogogo ba lọ da ẹmu. Tẹlẹtẹlẹ awọn ara Orun ti şe ikilọ fun Ogogo Ẹlẹmu wipe bi o ba ti gbe ẹmu kalẹ, ko gbọdọ duro, ki o ma lọ.

Lọjọ kan, Ogogo Ẹlẹmu bẹrẹ si şe ojojo, Ọya ọmọ rẹ papa nşojojo. Gẹgẹbi adehun ti nwọn ba Ogogo şe ko gbọdọ ma gbe ẹmu wa lọjọ kan ayafi ki o ti sọ fun wọn tẹlẹ. Bẹni aisan ko nwi fun ni tẹlẹ ki o to de, agbe Ẹlẹmu Ogogo dide o ta gọọ lọ sọdọ Ẹlẹmu kan, aladugbo rẹ, ki o ba on da ẹmu, ki o si gbe lọ sinu igbo Irumọlẹ fun awọn ara ọrun.

Inu awọn Ẹlẹmu dun, nihin ni nwọn gbero lati ba iṣẹ rẹ jẹ, aladugbo rẹ gbe ẹmu na lọ sinu igbo Irumọlẹ, nigbati o de ibẹ o wipe "Ara Ọrun, ara ọrun, mo gbe de o, emi Agbe Ẹlẹmu Ogogo"

Awọn ara Ọrun si dahun wipe, "gbe ẹmu silẹ ki o gbọnre" Ọkunrin na gbe ẹmu silẹ tan, o si lọ fi ara şoko lati ri iru awọn enia ti yio wa mu ẹmu na. Awọn ara Ọrun bẹrẹ si de lọkọkan, olori kan, meji, mẹta mẹrin ati bẹbẹ lọ.

Nigbati Olori mẹwa de ara fuu o si wipe "ha ebubu enia, Irẹ nrun 'gbogbo wọn fi imu leko, nwọn gborun enia, nwọn si dahun wipe, Irẹ nrun, irẹ nrun irẹ nrun, Nwọn bẹrẹ si wa inu Igbo Irumọlẹ lati mu oluwa rẹ, bẹni aladugbo ti o gbẹmu wa ba tu puru ki o to di wipe ọwọ awọn ara ọrun tẹ ẹ, o ti sare kọja ẹnu ala araiye ati ara Ọrun, ọwọ wọn ko si le tẹ ẹ mọ.

Nigbati Aladugbo na dele, o jişẹ fun Ogogo pe on ti gbe ẹmu fun wọn nwọn ni ki on ma lọ. Ara Ọya ọmọ Ogogo lo kọkọ fuyẹ lọjọ keji Agbe Ogogo na fuyẹ. Ogogo mura lati gbe ẹmu lọ fun awọn ara ọrun Ọya ọmọ rẹ fẹ ba lọ, şugbọn Ogogo baba rẹ kọ.

Bi Ogogo ti bọ soju ọna bẹni Ọya parada o di ẹiyẹ o si tẹle baba rẹ, Nigbati o de ọhun o wipe "Ara ọrun, ara ọrun mo gbe de o, emi ẹlẹmu Ogogo. Nwọn si da a lohun wipe, gbe silẹ ki o rodo.

Agbe Ogogo wa fura nisisiyi wipe aladugbo on ti ba nkan jẹ o si mura lati fori ran ijangbọn ti o ba şẹlẹ. Awọn ara ọrun bẹrẹ si de lọkọkan olori meji, mẹta, mẹrin titi de mẹwa olori wọn nwọn bẹrẹ si wọ ijakadi pẹlu Ogogo, nşe ni o si nda wọn ni ada şẹ lọrun. Olori mẹwa lo wa da Agbe Ogogo ni adapa.

Olori mẹwa fi ọun jawe, o fi osi ja, o fun si awọn tirẹ loju gbogbo wọn jidide, olukuluku pada si ọrun lati mu nkan ti nwọn o fi se Ogogo, Ọya fo wa silẹ, o mu ewe na o fun si baba rẹ loju o jidide o si pada sile.


**Ma Ka Iwe Irohin Eleti - Ofe**

**Ki O Si Polowo Oja Re Sinu**

**Iwe Irohin Aladun Yi**



**Blackpod Capsid**

**Ki O le pa'no arun ara igi Koko wonyi, Ma lo:--**

ẸRỌ TI A FI NFỌN EGBOGI SARA IGI KOKO

**Mysto Spraying Equipment**



Eyiti oni Ontẹ MYSTO MODEL NO. 159
Galọnu mẹta ni omi egbogi to ngba. ẹrọ l'o nfọn omi rẹ.

Eyiti oni Ontẹ "UNAMYST"
Galọnu mẹta ni omi egbogi to ngba, ọwọ ni a fi nyi ẹrọ ti o nfọn omi inu rẹ.

A le ri awọn Irin - Işẹ rẹ ra ti o ba bajẹ ni owo pọku.
Fi ẹrọ wọnyi lo:-

Egbogi ti a npe ni "PERENOX" ati "PEREPOD" fun arun Adu.

Lo "DIDIMAC" 25 fun arun kokoro miran to nba Koko jẹ
O wa ni gbogbo ẹka Şọbu,

**The United Africa Co. of Nigeria Ltd**
**ati U. A. C. (TECHNICAL) LTD.**

## Jamba Moto Sele

A gbọ irohin buburu kan wipe Mọto akẹru kan to ko ẹru ekuro kun bamu-bamu pẹlu awọn ero ni o ṣubu sinu koto niwọn ibu-sọ mẹsan larin ọna Ilọrin si ilu Ajasse

Enia mẹwa ọkunrin me-ji ati Obirin mẹjọ ni a gbọ wipe o ku sinu jamba yi.

Lọwọ jamba moto Olu-wa rere gba wa

## Lagos Race club

(ubẹrẹ loju ewe kini)

| | |
|---|---|
| " " | O9786 |
| " " | O1505 |
| " " | O583 |
| " " | O4164 |
| " " | O5880 |
| " " | O7004 |
| " " | O11968 |

AWỌN ENI WỌNYI YIO GBA £3. 3s 0. (Consolation Prizes.)

| Ticket No. | 16815 |
|---|---|
| " " | 4024 |
| " " | 9988 |
| " " | 2339 |
| " " | 17562 |
| " " | 1017 |
| " " | 5642 |
| " " | 12818 |
| " " | 11657 |
| " " | 2370 |
| " " | 10769 |
| " " | 9805 |
| " " | 4191 |
| " " | 11359 |
| " " | 6189 |
| " " | 7091 |
| " " | 6137 |
| " " | 10306 |
| " " | 4803 |
| " " | 12156 |

## Iya Aje Nka!

Lowurọ ọjọ Jimọ (Friday) ni ariwo sọ Gee ni opopo Kosọkọ Street, ti awọn ọmọde ngba riyẹriyẹ lẹhin Iya Ajẹ kan ti o nka awọn enia ti o ti ran lọ s'ọrun alakeji aremabọ.

Ọpọlọpọ ni ojulumọ enia ti iya oloju buruku yi ka wipe on ni on pa wọn. Omi Idọti ati oko siso ni awọn ọmọde da bo, ọpẹlọpẹ awọn enia to dabobo ni kojẹ ki wọn f'oko pa on na. Olukuluku ni yio jere isẹ rẹ.

## Irohin Ile Ejo

IBADAN. Ni kotu ilu Ibadan ninu ọsẹ yi ni ọdaran kan gbe sọ fun Adajọ wipe ki o wo ti Iyawo on to loyun ki o ṣanu on, nigbati nwọn mu ọdaran na wa fun ẹsun ole.

Ni ọjọ kan ninu oṣu yi ni a agbọ wipe ọdaran na wọ'le Ọgbẹni Daniel Bọlarinwa ni Abule Ẹgbẹda ti o si ji awọn awọn aṣọ bi oni Pọnun marun.


## Ogun Aran (Ejo Inu)




Aradan Worm Expeller jẹ ogun aran pataki fun ọmọde ati agba, ọkunrin ati obinrin. Ra igo kan lati ya gbogbo awọn aran buburu ti o nba ọ ja ninu danu. Bi o ti npa aran, bẹni o npa ẹyin wọn. Wa ra tirẹ ki o to tan. Igo kan jẹ 2/6d. Owo-Ọkọ si jẹ 1/-.

THE ẸGBA TRADING
ARADAN STORES,
18, Denton Bridge Street,
P.O. Box 2, Ebute Metta.



## Kere o!

A ti ni orişirişi ogun Germany to sẹsẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos



# LO EGBOGI ATATA Lati Dabobo Eso KOKO Re






LO ẸRỌ AFỌN-OGUN TI A NPE NI

## FOUR OAKS

X. O Dara Pupo

X, On Ni Ero To Dara Fun Ogun Fifon Sara KOKO Ti O LE Ra.



ẸRỌ AFỌN-OGUN TI A NPE NI FOUR OAKS YI MBE NI ILE ITA'JA AWỌN ẸGBẸ ALASOWỌPỌ TA ỌJA KAKIRI NIGERIA

THE CO-OPERATIVE SUPPLY ASSOCIATION LIMITED
COOP
WESTERN NIGERIA


Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P.O. Box 467 Lagos Phone 23??